# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 582 FRIDAY APRIL, 17 1964 (2D)

## Ọkunrin Kan Yin Ọrẹ Rẹ Ni'bọn

ILARO: — Idaamu ala ba gbogbo enia ti o wa nitosi nigbati nwọn gbọ iro ibọn ninu igbo ti nwọn si gbọ igbe ọkunrin kan ti o nkigbe ninu igbo na ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kerinla oṣu kerin ọdun yi.

Irohin awọn ọlọpa Ilaro fi ye wa pe, Ọkunrin kan ti oruko rẹ nje Adigun Ogundipẹ ati ọrẹ rẹ Ọgbẹni Mathew Daramọla lo jijọ da gbere ni ile wipe awọn nlọ ṣe ọdẹ ninu igbo kan ti o wa nitosi.

Irohin na tun ṣe alaye pe, nigbati awọn mejeeji de inu igbo na, nwọn dagbare fun ara wọn, nwọn si ṣe ipinnu ibiti nwọn ti fẹ pade nigbati nwọn ba ṣe tan, awọn mejeeji si wọ inu igbo lọ olukuluku si ọna rẹ.

Ṣugbọn ko pẹ pupọ lẹhin eyi ni Adigun Ogundipẹ gbọ ti kinikan nru inu igbo, nitosi ibiti o gbe ti nṣe ọdẹ tirẹ, ṣugbọn ko ri ara an na ti o nru inu igbo.

Nigbati o si wo yika ti o ri ọkankan ibiti nkanna ti nru igbo ni o ba ta ibọn si ọkan ibẹ ko si gburo nkankan ṣugbọn nigbati ode ibẹ ti oba ọrẹ re Matthew nile ninu agbara ẹjẹ ti o si nya eon paka pẹlu ibọn ti o dimọ ọwọ sinsin.

Lẹṣẹkẹṣẹ ni ọkunrin na ba sare lọ si Teṣan ọlọpa ti osi lọ sọ ohun ti oṣẹlẹ si ọrẹ rẹ ninu igbo awọn ọlọpa ti da ọkunrin na duro si Tesan nwọn si gbe oku ọkunrin na lọ si ile-iwosan lakulaku.

OLU. AYỌỌLA SỌ PE

# ADAJỌ ṢE AṢIṢE NINU IDAJỌ RẸ!

**EKO:—** Gbogbo Ile lo palọlọ ti ẹnikẹni ko si sọrọ nigbati ọgbẹni Olu Ayọọla, ọkan ninu awọn Agbẹjọro Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ o nsọ fun Ile ẹjọ gigajulọ ni owurọ ana ọjọ Ọjọ'bọ ti iṣe ọjọ kerindinlogun oṣu yi pe, "adajọ Agba Ọgbẹni G S Ṣowẹmimọ ṣe aṣiṣe ninu idajọ rẹ" nigbati o sọ ninu idajọ rẹ pe, Ọgbẹni Ọrẹdẹhin mọ pe, awọn enia kan nlọ si Ghana lati lọ kọ iṣẹ ogun ki o to san owo fun wọn.



Oloye Sowẹmimọ

Ọrọ yi ni ọgbẹni Ayọọla mba ẹwọn adajọ Ile ẹjọ na sọ ni owurọ ana nigbati Ile ẹjọ na bẹrẹ ijoko wọn eyi ti iṣe ijoko ọjọ karun.

Ọrọ awọn enia mẹta pere ni ọgbẹni Olu Ayọọla le fi ẹnu kan ni ana ki Ile-ẹjọ na to pari. O si sọrọ fun odidi wakati mẹta ati abọ.

Ọgbẹni Ayọọla sọ pe, "adajọ ṣe aṣiṣe lati ju ọgbẹni Lawanson si ẹwọn ọdun meji", lori ẹsun pe, o wa ninu ipade ti ọgbẹni S. G. Ikoku ṣe, ati wipe, o tun fun ọgbẹni Morohundiya ni ọgọrun pọnun.

Ọgbẹni Ayọọla ṣe alaye fun ile ẹjọ pe. ko si ninu ẹjọ awọn ti o wa jẹri fun Ijọba, bẹni Ọgbẹni Lawanson ko sọ pe on san owo fun Morohundiya gẹgẹbi adajọ ti ṣe sọ ninu ọrọ rẹ.

O wa pe akiyesi awọn adajọ na si Oju ewe 28 iwe idajọ lati lọ wo ẹjọ ti adajọ da, ki nwọn o le ba gba pelu on pe, "Adajọ ṣina" ninu idajọ rẹ.

O ni, ninu iwe idajọ na adajọ wipe, Ọgbẹni Lawanson lo kọ orukọ gbogbo awọn enia ti nwọn wa si ipade na silẹ, ṣugbọn ninu eri ti Ọgbẹni Richard Babalọla wa jẹ ni Ile ẹjọ lo jẹki awọn ri idi okodoro ọrọ na, awọn si mọ pe ọrọ na yatọ si idajọ adajọ.

Ọgbẹni Olu. Ayọọla sọ pe Babalọla ti o wa jẹri sọ fun Ile ẹjọ pe, o yọ iwe ti nwọn kọ orukọ awọn enia na si ninu apo ni, ko sọ wipe, on lo kọ gẹgẹbi adajọ ti ṣe wi ninu idajọ rẹ.

Olu. Ayọọla tun ṣe afikun pe, ẹri Babalọla lo fi han wipe, nwọn ko lọ si Ghana lati lọ kọ iṣẹ ogun, ṣugbọn nwọn lọ si Ghana lati lọ kọ bi a a ti iṣe iṣe akọwe ni.

O ni nwọn tun sọ fun awọn enia na lati le mura silẹ, nitoripe igbakigba ni nwọn le lọ si gbogbo awọn ilu ti o wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Afirika, lati lọ wo o awọn ẹgbẹ Oselu ni ilu miran ti ṣe nṣe.

Nibiyi ni Ọgbẹni Olu. Ayọọla sọrọ de ti adajọ agba Ọlọla Vahe Bairamian fi da a duro, ti o si mbi ni awọn ibere ọkan kojọkan, eyi ti nwọn fa mọ ara wọn lọwọ to nkan bi iṣẹju mẹdogun.

Ariyanjiyan na pari nigbati Ọgbẹni Olu. Ayọọla ka lati inu iwe ofin lati fi gbe ọrọ rẹ lẹsẹ. Bi o ti ka tan ti awọn adajọ na si ri si ọrọ na ni nwọn ba rẹrin, nwọn si sọ fun un pe ki o ma a ba ọrọ rẹ lọ.

Lẹhin eyi ni Ọgbẹni Olu. Ayọọla wa bọ si ori ọrọ ti Ọgbẹni Ọrẹdẹhin ẹniti iṣe akapo ẹgbẹ Afẹnifẹre.



Oloye Awolọwọ

O ṣe alaye pe, "adajọ ṣina ninu idajọ rẹ" nitoripe ẹjọ ti o da ti o fi ṣe idajọ ẹwọn fun Ọrẹdẹhin yatọ gedegede si idajọ rẹ.

Gbogbo ile ẹjọ lo tẹti leko nigbati Ọgbẹni Olu. Ayọọla ṣe alaye pe ẹjọ Ọga kan ti o kesi ọmọ ọdọ rẹ pe ki o ba on mu ida rẹ wa. Nigbati o gba ida ọmọ ọdọ na o lọ fi ṣe iṣe ibi nwọn si ragabu rẹ.

Olu. Ayọọla sọ pe, o yatọ si Ọga ti o pe Ọmọ Ọdọ rẹ pe ki o ba on mu ida on (Ọga) wa ninu ile, ti Ọmọ-Ọdọ na si fun ti o wa lọ fi ida na ṣe iṣẹ ibi ti nwọn si mu.

Ọgbẹni Ayọọla ni Ọga kan lọrọ ida ṣe iṣẹ ibi nigbati Ọga keji lo Ọkunrin rẹ gẹgẹbi o ti ṣe wuu nitoripe on lo ni nkan rẹ.

O ni be gẹgẹ ni ọrọ ti Ọgbẹni Ọrẹdẹhin jẹ nitori pe nwọn ko iwe fun awọn enia na wa si ọdọ Ọrẹdẹhin pe ki o san owo fun wọn gẹgẹbi aye rẹ akapo, o si san owo fun wọn ko mọ ohun ti nwọn fẹ fi owo na ṣe ki isi iṣe iṣẹ rẹ lati ma a bere, ṣugbọn iṣẹ rẹ ni pe ti o ba ti ri iwe lati ọdọ akọwe ki o san owo fun wọn.

O ni o wa ya on lẹnu bi adajọ tiṣe sọ ninu ọrọ rẹ pe, "Ọrẹdẹhin san owo fun wọn o si sọ fun wọn pe, gba ma a lọ si Ghana" o wa pe akiyesi awọn adajọ si idajọ adajọ na ni oju ewe kẹrindinlogun (page 16)

O tun ṣe alaye fun ile ẹjọ pe ki iṣe ohun ti o rọrun lati ṣe iranti gbogbo awọn ti o ba wa ngba owo lọwọ enia o ni awọn miran yio wa gba owo ti akapo ẹgbẹ ko tilẹ mọ ri on ti o gbọdọ ri lọwọ wọn ki o si gba silẹ ni iwe ti akọwe kọ fun awọn enia

WO OJU EWE KẸFA

# Ile Ọti Mimu Di Ile Adura !

**EKO:-** Gbogbo enia to nkọja lọ ni opopo Glover ni nwọn nya ẹnu wọn ti itọ fẹrẹ le mọ bọ silẹ lẹnu wọn nigbati nwọn ri ile ọti mimu kan to njẹ "Ọwọ Bar" ti o wa di ile ijọsin fun Ọlọrun ti nwọn ngbọ ilu ti o yatọ si ti awọn olorin ti nwọn si ngbọ Alleluyah ni ẹmẹwa. Ha! ṣe ọpọlọpọ ti ẹlomiran nsọ pe, iṣẹ Ọlọrun nitotọ awa mọ ridi ni iṣẹ Olodumare. Aṣe ile yi le di ile adura, ogo ni fun Ọlọrun ni oke Ọrun ati ni aiye, alafia fun gbogbo enia.

Ni ọjọ karun oṣu kẹrin oṣu yi ni Woli Obinrin kan ti Ọlọrun yan gẹgẹbi agbẹtẹru ọrọ rẹ, orukọ rẹ ni Woli Obinrin G. C. O. Cole ẹniti o ngbe nọmba 4, Tokunbọh Street Eko.

Ni deede agogo meji ọsan ni awọn Aladura ati awọn enia patakipataki ti pe simu-simu sinu ile Ọlọrun na ti ẹsẹ ko gba ero rara. Awọn Woli wa ninu aṣọ oye wọn lọkunrin ati lobinrin ti gbogbo nkan lọ dada.

Isin Ișile Ọlọrun na bẹrẹ ni deede agogo mẹta ọsan, gbogbo ile ati ita kun fun awọn enia lati Ibadan, Abẹokuta, Ilesha, Akurẹ, Ọyọ, Ijẹbu-Ode a ko le sọ awọn ti o wa lati Mushin, Shomolu, Agege, Shogunlẹ, Yaba. ati Ebutemẹtta.

Isin na bẹrẹ pẹlu orin Akunlẹkọ lẹhin na ni woli Abiọdun gba adura Ijuba ati ibẹrẹ isin, nwọn tun kọ orin, ni awọn enia mẹta ba tun gba adura pataki lori Ọpẹ fun awọn ore ti Ọlọrun ti ṣe fun wa ti o dawa si titi di ọjọ oni ti a si tun wa laiye, wa laye ti Ișile yi ko ba wa ninu erupẹ.

Adura keji ni fun awọn ojiṣẹ Ọlọrun ni gbogbo agbaiye ki Ọlọrun majẹ ki emi buburu lo wọn, ki Ẹmi Mimọ Ọlọrun mọ na nwọn gbẹ ki nṣi mọ fi iṣọ Rẹ sọ wọn ati Ẹkẹta adura pataki fun ẹniti Ọlọrun lo lati da ijọ yi silẹ ki Ore-ọfẹ ati alafia Oluwa ki ọmọ ba gbe pẹlu idile rẹ.

Adura Ibukun, Alafia, Abo, Agbara Ẹmi Mimọ Ifẹṣẹ mule Ijọ ati Imọlẹ Ọlọrun lati mọ se imọlẹ awọn Olusọ agutan Rẹ.

Lẹhin gbogbo iwọnyi ni Woli E. O. Ọdunoyọ wa sọ pe, ẹniti awọn fi ṣe alaga loni, airotẹlẹ ni o lọ si ilu Ọba, o kọwe ransẹ pe, inu on dun si ipo ti ẹ yan on si sugbọn gẹgẹbi ọrọ na ti ṣe jẹ arun oju gbogbo nyin ni ẹ mọ nkan ti ko jẹ on wa' ẹmi on wa lọdọ wọn, ẹni na ni Ẹni ọwọ G. Olu. Emmanuel.

Ṣe bi a ko ba ri adan mọ, ọran yan ni ki a fi oobẹ sebọ, ni wọn ba wa fi Ẹniọwọ E. A. O. Osisanmi se alaga ọjọ na, on ni ọga agba ti o wa nile iṣẹ awọn ti to nyẹ iwe owo Ijọba apapọ wo. Ati Alaga obinrin ni Iyaafin Iya-ninura Ally Oyeneyin.

Ẹniti o mu ọrọ Ọlọrun wa ni Woli E. O. Ọdunayọ, o si ka pupọ ninu ọrọ Ọlọrun, o ka Romu 3; 8. ati Romu 8; 30. Ori ọrọ rẹ ni pe lori Ipinlẹ ti Jesu ti fi lelẹ ni a nkọ ile le, lori, o wa ku si ọwọ wa awọn nkan ti afi nkọ ti wa boya erupẹ ni, bilọki, patako, biriki tabi koriko.

Nigbati Solomọni fẹ kọ ile fun Ọlọrun o lo orișirisi awọn ohun elo Olowo iyebiye sugbọn Jesu ti sọ di idẹra fun wa. O ti șe Ipilẹ nitorina ki a mọ șe ma awọn nkan ikọle ti yio jọna

Ni ibuje ẹran, ibi ti ko dara ni a bi Olugbala wa si, bẹ na ninu ile ọti ni a ti fi ile-Ọlọrun lelẹ ọpẹ ni fun Ọlọrun ibiti ko dara wa di ibi Mimọ loni, Ọpẹ nla ni fun Ọlọrun

Ti ẹ ba ri Woli ti gbo gbo iru ori rẹ dabi igbo ti nwọn ko le gbadura fun enia nitoripe gbogbo aṣọ wọn ni o nrun si ẹniti nwọn ngbadura fun ki a kiyesi daada nkan miran ti wọ. Ani lati jẹ mimọ bi a ti mọ pe, ẹniti a nsin mimọ ni.

Ki a mọ kanju ju Ọlọrun lọ, ẹlomiran tọya bi ko ba ti di ọnọ ogoji ọdun dada rẹ ko le ti de nigbati o ba ti di ọmọ ọdun mẹdọgbọn tabi marunlelọgbọn ni yio ti mọ binu si Ọlọrun a ni on ko sin Ọlọrun mọ, lati iye jọ yi, nigbati ki ṣe on nikan Ẹ mọ ṣe kanju ju Ọlọrun lọ

Nipa kikanju ju Ọlọrun lọ, ẹlomiran nfi ipa kọle, ẹlomiran nfi tulasi ra mọto asinwa asinbọ loju ẹmirẹ nṣe ni nwọn yio lu ile na ni gbanjo mọ lori, nibiti o gbe ngbadun mọto rẹ kiri ni nwọn o ti da duro ti nwọn o si gba nidi rẹ. Ẹma jẹ ki a mọ fi ikanju ja ida lorikọ.

Woli ti o da ijọ yi silẹ lati ọdun bi mẹtala (1951) sẹhin ni Ọlọrun ti nlo, ti o si nfi suru ba iṣẹ na bọ ti ti di oni yi ko kanju ra ra, loni kọ? Asiko na de.

Ti a ba lọ wo Orin Dafidi ori kẹrinla-logbọn ao ri adura ti o daju fun awọn olododo Gẹgẹbi awọn ẹlomiran ti ngbadun adura ti a ba ti gbebẹle Ọlọrun gbogbo nkan ni yio mọ lọ deede fun wa. Ile Ọlọrun mọmọ dara o, Gbogbo wa ki nwọn bi sinu Aladura emiran lati inu Ijọ Eleto, Onitẹbọmi C M. S. Aguda ati bẹebẹ lọ ni o wa dapọ mọ ẹgbẹ aladura

Bi o ti nsọrọ kan tabi meji ni nwọn nfi orin si larin. "E mi duro ti baba ko le sọ'ran mi dayọ".

Kini yio wa ya wa kuro lọdọ Jesu, ebi, iya, ihoho siri aṣọ wọ ni? Ka nọ ri Jesu ni awa yio sin titi ọjọ aiye wa.

Ọpọlọpọ ni iponju olododo sugbọn Oluwa gba ni nu gbogbo wọn.

Ni ipari isin ni akọwe Ijọ "The Light of Christ Church" Ọgbẹni S. A. Adedokun dupẹ lọwọ gbogbo awọn ti o wa ati awọn ti ko le wa ti nwọn ran enia wa paapa awọn ti o fi iwe ranṣẹ ati gbogbo awọn enia ti o dawo fun ikọle Ọlọrun titun.

Nwọn fi onjẹ dabira, agbọn ati ẹwa, raisi lọbi rẹrẹ ajẹti ati amu.i ni wọn fi onjẹ ati ọti aladun ṣe ni ọjọ na Ọlọrun yio mo ju to Ijọ rẹ. Amin.



Aworan oke yi ni ti awọn ọmọ ẹgbẹ akorin ti Ṣọọṣi ẹlẹja ti Oke—arin

---

**Ẹ Ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ Fun Irohin Aladun**

# IWE SI OLOTU

## Ijębu-Ode Nfę Amojuto Ijǫba

Inu mi yio dun bi ę ba le gba mi ni aye ninu iwe Oloyin mǫmǫ Irohin Imǫle lati ke si igbimǫ ti işe abojuto ilu Ijębu-Ode lati bojuto awǫn oju na ti gbogbo re ko si dara fun awǫn oni moto papa julǫ awǫn ti nfi ęsę rin ni irǫlę.

Eyi to je ohun pataki ni ǫrǫ omi ęrǫ to fi je pe igbagbogbo ni nwǫn ma nti awǫn omi ęrǫ to wa larin ilu.

Ilu awa to nsan owo ori yio dun bi awǫn igbimǫ na ba le ba wa şe ayewo awǫn nkan wǫnyi.

Awǫn nkan to tun je ohun pataki pelu ni nipa ina to wa larin opopo ilu. Ǫpǫlǫpǫ awǫn Opopo ilu ni ina ko ti de titi di isiyin, inu wa yio dun bi awǫn Igbimǫ to nbojuto ilu ba le ba wa mojuto awǫn nkan wǫnyi.

Emi ni
ADEBAYǪ FIJAMI
Ijębu-Ode

## Ę ye fi Ęran Ǫdun Ileya ja

Olotu, ki işe ohun ti o dara rara lati ma a şe ika si ara awa ǫmǫ enia ki i si şe ohun ti o dara rara ati rara fun awa ǫmǫ enia lati ma a fi ika şe awǫn



Alhaji Y. A. Disu

ęranko Olǫrun ko fę iwa ika, O korira iruję iwa l'e ę pupǫ.

A bę ęnyin ǫdomǫde pupǫ pe, ki ę maşe fi awǫn agbo, Ęran ǫdun Ileya ba ara won ja.

Ę ye fi wǫn kan mǫ, eyi ko dara rara o.

Ęnyin obi, ę maşe gba awǫn ǫmǫ nyi laye lati ma a fi awǫn ęran nyin ja.

Emi ni
ALHADJI Y. A. DISU

## Shagamu Nfę Omi-Ęrǫ

Inu mi yio dun bi ęba le gba mi ni aye lati kesi Ijǫba ibilę ti ilu Shagamu lati ba wa tete şi omi ęrǫ ilu Shagamu ti nwǫn ti ti pa ni nkan bi Ǫdun kan sęhin.

Nipa ǫrǫ omi yi si je wahala fun enia ilu na ati papa julǫ omi ti asi nmu na ko si dara rara ru omi bę le fa arun to lewu pupǫ si arin ilu

Inu wa yio dun bi awǫn alakoso Ijǫba na ba le ba awǫn ara ilu şe a ęwo yęg: bi omi ęrǫ na yio ti se di mimu fun awa ara ilu

Mo dupę pupǫ o Olotu
Emi
Mufutau Oshilaja
Shagamu

## A Dupę pupǫ

Inu mi yio dun bi ę ba le gba mi ni aye lati dupę pupǫ lǫwǫ Ijǫba Ipinlę Iwǫ Orun Naijiria fun ina Eletriki ti nwǫn şęşę şe de Bariga laipę yi.

Awa ara ilu na si dupę pupǫ, ati pe inu wa yio dun bi Ijǫba ba le ba wa tun awǫn oju ǫna ilu na şe ti yio fi wulo fun awǫn oni moto papa julǫ fun awǫn oni kękę pelu awǫn ęlęsę nitori pe asiko ojo nsunmǫ tosi bayi,

Ǫna Bariga lati Shomolu ni ayęwo pupǫ lati le tete şe itǫju awǫn ǫna na. Toba ti di irǫlę ǫna Bariga lewu pupǫ lati rin, inu wa yio dun bi Ijǫba ba le şe amojuto ǫna na.

A dupę o
JOHN ADELEKE
Bariga-Shomolu

## Igbaja Ę da Kę Ni

Inu mi yio dun pupǫ bi olotu iwe Irohin Imǫlę ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe rę Oloyin mǫmǫ lati ba awǫn Ǫmǫ ilu Igbaja sǫrǫ atata lori bi ilu wa yio ti şe ni ilǫsiwaju, ti a o si ni mǫ gbe anfani wa sǫnu mǫ.

Ninu iwe Irohin Imǫlę lati gbǫ wipe Ijǫba Ipinlę Ariwa fę kǫ ile-iwosan si ilu wa a si gbǫ pe nwǫn tǫ Ǫba ilu wa lǫ lori ǫrǫ na iyalęnu lo je nigbati a gbǫ pe Ǫba ilu wa ko fesi rara ti nwǫn si gbe lǫ si ilu Yaru

Bęna ni a tun ngbǫ labęlę pe nwǫn tun fę gbe ile-ęjǫ Ijǫba ibilę lǫ si Yaru o je nkan ti o nşe wa ni ka fi lǫpǫ lǫpǫ. Gbogbo awa Ǫmǫ ilu Igbaja lo nda owo ori si apo Ijǫba Ipinlę Ariwa.

Mo a nke si gbogbo ęnyin Ǫmǫ Igbaja pe, ki ęje ki a mura si awǫn nkan wa ki o mǫ ti oju wa baję mǫ, nitoripe a nfę ki Ijǫba Ipinlę Ariwa ki o ran wa lǫwǫ ni ki nwǫn mǫ gbe awǫn anfani ilu wa fun ilu miran mǫ.

Olotu mo dupę aye ti ę gba mi Okǫ Oba ko ni sa nyin lęsę.

Emi ni
S. B DAN ALHAJI
Igbaja


## Ęgbę Imǫlę Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awǫn ǫmǫ ęgbę Imǫlę Aiye ni awǫn ǫjǫ wǫnyi, ǫjǫ Aiku ti işe ǫjǫ kǫkandinlogun oşu yi ati ǫjǫ kerindinlǫgbǫn oşu yi kanna (19/4/64 ati 29/4/64 eyi ni ǫjǫ mejǫ mejǫ) ni deede agogo meji ǫsan ni nomba 16, Bamgbose Str Eko.

Ao si tun fi tayǫtayǫ gba awǫn ǫmǫ ęgbę titun ti nwǫn ba wa si ipade lati je ǫmǫ ęgbę.

Ki ę tete de o.

LATIFU BABALǪLA
Adele Akǫwe

# Kere o!

Fun anfani gbogbo ęnyin onişowo, Iwe Irohin Imǫlę yio şe ipolowo awǫn ǫja nyin fun nyin ni ǫsę kan gbako ki ǫdun Ileya o to de ati lęhin odun ki awǫn onibara nyin le ba nyin ra ǫja ti ǫdun Ileya ti mbǫ yi.

Awǫn Aşoju wa yio ma a lǫ kakiri lati bere fun awǫn ti o ba fę lati polowo ǫja wǫn ninu Iwe Irohin wa

Owo pǫoku ni a ngba, dan wa wo lękan ki o şribi aje re yio ti ta to, Ijafara lewu o

# EGBOGI JĘDIJEDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jędijedi rę gbe wa lara re si nyǫ o lenu nigbagbogbo. Ibę ni a npe ni "omusu tabi Ihoidi enia ibiti a ma ngbe şe igbǫnsę. Arun Jędijedi je ǫkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ǫkunrin ti o si lagbara pupǫ lati şe iwosan rę patapata.

Ǫpǫlǫpǫ egbogi ni nwǫn nta kakiri lode nisiyi ti wǫn a ma polowo wǫn fun iwosan rę şugbǫn boya la leri mewa ninu ǫgǫrun ti o le şe iwosan arun yi daradara, Awǫn ęlomiran lero wipe bǫya bi wǫn ba lǫ si ile Dokita lati lǫ ke eyiti o ba nyǫ jade lati omusu ku ni pa bę awǫn o bǫ lǫwǫ rę patapata.

Şugbǫn awa ko ro bę rara. Lęhin ǫdun diẹ iyǫnu rę yio si tun bęrę bakana. Orişirişi Jędijedi ni o wa ekini ti o bęrę nipa aiko ma şe igbǫnsę dede tabi lojojumǫ. ęlomiran nipa ijoko ni ojukanna şęlu lojoujmǫ tabi gigun kękę ologere (Basikulu, pupǫ ęlomiran ewe nipa Jije Şuga tabi oniruru ohun adidun pu poju nigbakugba. Jędijedi orişirişi ni o wa, ewo ni tirę? Bi o nyǫ ade inu omusu, tabi ti o ba nmu ęję wa lęhin igbǫnsę, tabi ti o ba nyǫ ti o ba şe igbǫnşę tan ni, tabi ti nrin ǫ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "CYCLOVEN" ti awǫn Oyinbo Jamani şęşę wa idi rę ki o si danwo orişi męta ni o daju wipe iwǫ yio bǫ lǫwǫ Jędijedi na pata alafia yio de si ekeji rę ko si ninu gbogbo egbogi taagboro ilu Naijiria jakejado. Bere rę ni:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

# Riro Ni Ti Enia Şişe Ni Ti Ọlọrun

Lati ọwọ MAJẸKOBAJẸ ỌMỌ ILẸ IGBOMINA

Mo ki ilu ọtun Oro pupọ, nwọn ku işẹ, nwọn si tun ku suru, dajudaju suru lere pupọ, o mu mi ranti ọkunrin kan ti o ma nkọ orin nigbati a ba wa ninu ọkọ oju omi lọna ọja Ejirin ni ọdun (1930) pe, Ọba ko ni lọ ni ilu, şugbọn gẹgẹbi ọrọ Oluwa arinurode Olumọ ọkan yio şẹ ni ọdun (1931) ni o ba kuro ni ilu na pata pata.

Bakanna ni ọkunrin kan ma nsun rara laiye atijọ, ti o ba nkọ orin rẹ na, a ma sọ pe, bi on ba ku loro aiye on yio lọ si oro ọrun kẹ wa wo işẹ Oluwa, ko pẹ pupọ ni o ba tẹ, ao gba ọja, a ko gba ọjade, akọrin yi ko de Oro mọ.

Ẹhin-ọrẹ-hin lo wa bẹrẹ orin rẹ miran pe, ilu kekere ọkọ ilu bantabanta, ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ mo fẹ şe apejuwe gẹgẹbi ilu na ti mọ nigbana.

Ilu Şogunlẹ yio jẹ ọkọ ilu Eko, mo bẹ awọn ara Şogunlẹ ki nwọn fi ori jin mi, ọrọ lo mu ọrọ wa o. O tun kọrin pe, ilu kekere to ngba ri o nşa oko, ha! ọrẹ mi olorin, ẹlulu ajẹ Igba ogun ma ku. Bi ẹiyẹ oko ti nfo ni ẹlulu nfo bi?

Mo tun bere ọrẹ mi kan to njẹ pẹtẹpẹtẹ ti a nna ni papa, mo ki gbogbo ẹnyin Ọtun Oro, ẹ ku ọpọ suru, ki ilu kekere şe ọtẹ titi ki nwọn tun wipa ọkọ akero ko gbọdọ ko ero wọ ọja Oro.

Ẹnyin Oro, ẹ ku işẹ o, ẹ ku inawo mọto, Oluwa ko ni gbe awamọto na şubu amin ati awọn to nwa mọto ilu miran Oluwa yio wa pẹlu nyin. Ẹo tun ma gbọ itumọ awọn orin lọfọ mi-an

Bi ale iya ẹni la to baba ẹni, baba ni a npe Oluwa Ọba ko ni ba ẹkun mẹsẹsan Oro ẹ.


## Congreve,s Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudu ara tabi aikotọ ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi - oju Ilaogun ara esẹ ara sisọn, ẹfọri abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo Obinrin gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

**Ammoniated Quinine Tincture**

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọki egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ aju wipe kosi ohun ti a le fi le egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji ti a ipe ri nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio şe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ opo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi aju didun tabi ti ọwa-ọfun didun, ati orişirişi omira pẹlu wọn mbẹ ni şọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone: 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)
ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street Yaba — Lagos


## ★ YẸ IRAWỌ RẸ WO ★

AQUARUIS (Jan 20-Feb 18) Şọra rẹ loni ki amodi ma ba yọ ọ lẹnu o dara ki o gba tẹgun lọ si oko kan, Iwọ yio yan ọrẹ pupọ larin obinrin ati okunrin, ija yio bẹ silẹ laria Iwọ ati awọn ẹbi rẹ.

PISCES (Feb 19-Mar 20) Akoko owurọ yio dara fun ọ ki o si dan gbogbo ero ti o ni lọkan wo, Lọwọ ọrẹ rẹ kan ti o ti nwa ọ lati ri ki o si sanu fun. Mase jẹki fari rẹ pọju.

ARIES (Mar 21 APL 19) Odara ki olo gbogbo ọjọ oni lọdọ ọrẹ rẹ kan nigbana ni iwọ yio ni ọrẹ titun ara rẹ yio ya yio si le pẹlu lati şişẹ şugbọn mase ba ẹnikan jiyan si ọrọ ti ko nidi.

TAURUS (Apl 20 May 20) Ibiti ara nfu ọ si ọna ko jẹ bẹ o dara ki o sun ki o si ronu ayafi ki o se pasiparọ awọn ọrẹ ti o ni nitori ki o ba le mu ọgbọn ori rẹ soji.

GEMINI (May 21-June 21) Ara rẹ yio ya ero rere yio si bọ si ọ ni agbari. Iwọ yio ri owo ko, ati ọrẹ pupọ, iwọ yio ni ọrẹ obinrin titun

CANCER (Juna 22-Jly 22) Ọjọ oni dara fun ilọsiwaju ẹkọ ẹsọ di owo re, maşe fi ọwọ rẹ fa işẹ ti ọwọ rẹ ko ni ka maşe ba ẹnikan jiyan

LEO (July 23-Aug 22) Maşe lo ọjọ oni ni ilokulo, o dara ki o lọ fi ara si oko kan fun Igba diẹ. Jẹ ki ẹbun ti nwọn o fun ọ loni jẹ itẹ wọgba lọdọ rẹ tayọ-tayọ

VIRGO (Aug 23-Sept 22) Ọjọ oni dara fun ọ lati şişẹ ọna ti yio jẹ itẹlọrun fun gbogbo enia nşe ni ki o lo ọgbọ ori nipa ọrọ ara rẹ, Iwọ o si ri irohin aladun gbọ labi ki o gba iwe,

LIBRA (Sept. 22-Oct,23) Maşe fi işẹ rẹ şere rara bofẹ bi idamu wa nibẹ, lọdubulẹ, kio sun, bi o ba dide jade lọ wo awọn ọrẹ rẹ, ni şişẹ bẹ ire mbe fun ọ nibẹ.

SCORPIO (Oct. 24-Nov. 22) Ma gba itọ ẹlomiran danu, Bio ba lọ se bi o ba jafara, afara yio ja ọ nipa rẹ, wadi.

SAGITTARIUS (Nov. 23-Dec. 21) Ko si ibalẹ ọkan fun ọ rara ailera si wa pẹlu rẹ, nitorina o yẹ pe ki o lọ dubulẹ ki o si sun bi idina ohun ba wa o yẹ ki o foriti.

CAPRICORN (Dec. 22-Jan. 19) Alafia ati ara lile lo jẹ tirẹ loni maşe ba ẹnikẹni jiyan. maşe şaşe rege.


AH! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

## An Eid-Ul-Kabir Dance

AT

FORSTER CENTENARY HALL

22, Ọduniami Street, Lagos. On Sunday 26th Apri 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest beats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/- Flat**

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboşe Street, Irohin Imọlẹ's Office Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta.

# Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye Tun Pegede !

EKO:- Irohin ko to afojuba ni ayẹyẹ ipade kini ti ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ṣe lẹhin ti nwọn ti tun ẹgbẹ na to ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu kẹrin ọdun yi ni ile-iṣẹ Irohin Imọlẹ Eko.

Nigbati o ti di owurọ ọjọ ti nwọn yio ṣe ifi oruko ẹgbẹ titun yi lelẹ ni awọn ọmọ ẹgbẹ ti nde lati Mushin, Agege, Ikẹja, Ifọ Itori, Idi-Oro, Yaba, Abule-Ijẹsha ati bẹẹbẹ lọ ti nwọn wa siilu Eko f u n Ipade pataki yi.

Gbogbo ẹsẹ ọmọ ẹgbẹ ati awọn ti o sẹṣẹ fẹ jẹ ọmọ ẹgbẹ ni o si ti pe sibi Ipade na ki oto to agogo mẹta ọsan ti ipade yio bẹrẹ.

Lẹhin ti ẹsẹ gbogbo wọn si pe sibi ipade na, ni Alaga na Ọgbeni J. Ọla. Okunlọla wa yan Ọgbeni R. A. Dunmoye lati fi adura ṣi ipade na.

Nigbati ipade na bẹrẹ, gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ ni o sọ orişirişi ọrọ iwuri, ti nwọn si sọ ẹdun ọkan nwọn nipa ilọsiwaju fun ẹgbẹ titun yi, nwọn sọ aiki nwa si ipade ati pẹlu nipa owo ẹgbẹ ti ki nlọ deede mọ.

Lẹhin ti gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ sọrọ tan ni Ọgbẹni Lẹtifu Babalọla ti iṣe Oludasilẹ ẹgbẹ na, ti o si ti jẹ akọwe Agba fun ẹgbẹ na tẹlẹ wa sọrọ nipa ohun ti o fa ifasẹhin ẹgbẹ na tẹlẹ o ni aiki nwa si ipade ati pẹlu nipa owo ẹgbẹ ti awọn ọmọ ẹgbẹ ki nda deede, on ni o fa a.

O ni ọpọlọpọ wahala ni on ṣe lati ri pe, ipade nlọ deede, on nfi iwe ipade ranṣẹ si awọn ọmọ ẹgbẹ ati pẹlu ọjọ ipade si tun njade ninu Irohin Imọlẹ, sibẹ awọn ẹgbẹ ki nwa. Nitorina o wa da ni imọran fun awọn ẹgbẹ titun yi pe ti a ba ti nwa si ipade deede on ni ẹgbẹ yi yio fi lọ si oke Ni ipari ọrọ rẹ o rọ gbogbo awọn ẹgbẹ lati ma wa si ipade, ki nwọn si jẹki asowọpọ fun ilọsiwaju ẹgbẹ ati paapa fun ilẹ wa O ni o tilẹ wa to asiko fun awa ọdọ ilẹ Yoruba lati jọ sowọpọ ki ale ma ja fun ẹtọ wa ninu Ijọba Apapọ Naijiria bi o tilẹ jẹpe a ki nṣe oṣelu, gẹgẹbi ofin ti fun gbogbo awọn ara ilu ni ẹtọ wọn lati ṣe nkan ti nwọn ba fẹ ni ọna alafia, nitorina gẹgẹbi awọn olorin ti nkọ: "Ẹ jẹki awọn ọdọ Yoruba ronu."

Lẹhin ọrọ rẹ ni gbogbo ọmọ ẹgbẹ wa fi ohun sọkan lati yan awọn alaṣẹ fun ẹgbẹ titun lẹhin ti ẹgbẹ ba ṣe ipade bi ẹmẹta ti olukuluku si mọ ara wọn.
Ki nwọn to wa mu ipade na de opin nwọn fi ara mọ pe ki a ma ṣe Ipade ni ọjọ isimi eyini ọjọ mẹjọ mẹjọ titi ẹgbẹ na yio fi fi idi mulẹ daada, bi o tilẹ jẹ pe ao wa sun siwaju ipade yio ma wa ni ọjọ isimi ni deede agogo meji ọsan.

Diẹ ninu awọn enia jankanjankan ti o wa si ipade na ni Ọgbẹni J. O Okunlola, Ọgbẹni Sulaimọn Cole, Ọmọba Saidu Olupo Ọgbeni James Ọlayiwọla Akande, Ọgbeni Lamidi Atanda, Ramọnu Adio Bakare, Michael Faloye, Salami Oloyede, Ọgbẹni J A. Alli-Bey, Ọgbẹni R. A. Dunmoye, Saidu Giwa Balẹ, Y. Mutairu, Josua Ademoye, Abudulai Awẹlẹnjẹ, Orlando T. Akins' ati ọpọlọpọ awọn enia ti aye ko si lati darukọ,

Awọn Alakoso Irohin Imọlẹ si fi jijẹ a ti mimu tẹ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na lọrun.


BI O BA NI

**Iwe—Tite**

*UN*

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

*ATI*

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
*OWO POKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ*


## Ẹgbẹ Irẹpọlodun Ọkanle Şi Ile - Ekọ Titun

IROHIN ko to afojuba ni ayẹyẹ eto işile ẹkọkewu titun ti awọn ọmọ ẹgbẹ Irepọlodun ati gbogbo awọn ara ilu ṣe ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹta oşu kẹta ọdun yi labẹ Alaga Ọgbẹni Oyebọde Dawodu ni deede agogo mẹjọ owurọ ni Ọkanle ilu kan ti ko jinna pupọ si Ilọrin.

Işi ile ẹkọ titun na bẹrẹ ni dede agogo mẹjọ owurọ ati pe gbogbo ẹsẹ awọn ọmọ ẹgbẹ na lope si ile ẹkọ titun na.

Ki ẹyẹ ọjọ na to bẹrẹ Alfa Imam Yesufu ni o kọkọ ṣe adura işile titun na Lẹhin eyi, ni ọgbẹni Oyebọde Dawodu ti o jẹ alaga ọjọ na si tun sọ ọrọ iwuri ati awọn iṣẹ ribiribi ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe si ilu Ọkanle, papa julọ fun ile ẹkọ titun ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ko (Okanle Islamic Centre) ti yio mu ilọsiwaju pupọ wa fun ẹsin Islam ni ilu Ọkanle

Alaga na si tun sọ ni ẹda keji ẹwẹ pe bi o tilẹ jẹ pe awọn ọmọ ẹgbẹ na jẹ ọdọ, o ni iṣẹ ti nwọn ṣe si ilu yi, pe yio jẹ ohun fun iranti awọn enia ilu Ọkanle.

Onirohin wa si fi ọrọ jomitoro lọwọ arakunrin kan Ọgbẹni Kọla Taylor Kọmọlafẹ ti iṣe alaga fun ẹgbẹ na, o si sọ fun onirohin wa pe awọn ọmọ akẹkọ kewu to wa ni ile ẹkọ na si ti to adọta le nigba ati pe awọn si nfẹ iranlọwọ awọn ara ilu na, nipa owo lati tun fi kọ ile ẹkọ miran ti yio tobi ju eleyi lọ nitoripe eyi ti wọn nlo bayi ko si tobi to ti o gba gbogbo awọn akẹkọ na

Eyi ni diẹ ninu awọn enia jakanjakan to wa sibi işile ẹkọ titun na ni Yesufu Olaleyẹ ti o jẹ Baba ẹgbẹ Ọgbẹni A. Atanda (Akọwe) K. A. Lawal ti o jẹ igbakeji Baba ẹgbẹ Kọla Taylor Kọmọlafẹ Alaga ẹgbẹ, Kọla Ajide Baba isalẹ, Sheu Ibrahim Yanus olori ẹgbẹ. Awọn ọmọ ẹgbẹ na si fi jijẹ ati mimu tẹ awọn enia to wa sibi ẹyẹ işile ẹkọ na lọrun.


## Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ

ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"

LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ŞINA TABI NA OWO INAKUNA. KI *O* LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubori gbogbo ẹda patapata" Amin·

**"WAS SALAM"**

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo ni oyẹ ki o ni na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA
*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*

MANAGER
N2/99 SITTU STREET
HIbadan

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 582 FRIDAY, APRIL 17, 1964 (2D)


## Ẹlẹmu Kan Ṣe Agbako Iku Mọto

IJẸBU-ODE:— Jinnijlnni dabo gbogbo awọn ero ti o wa ninu mọto akero kan ti o nsare bọ loju ọna Shagamu si Ijẹbu-Ode nigbati mọto na ya kuro loju ọna ti o si lọ ba ọkunrin kan, Alani ẹni ọdun marundinladọta ti o nṣe iṣẹ ẹmu, ti mọto na si pa nibiti o duro si.

Ẹ ti irohin na ṣoju rẹ ṣe alaye fun oniwe irohin wa pe, Ọgbẹni Alani Alli mbọ lati ibiti o gbe lọ da ẹmu, o gbe akerengbe ẹmu kan lori, o si fa akerengbe ẹmu kan lọwọ o duro si ẹgbẹ ọna awọn si nwo o ni okere.

Ṣugbọn nigbati mọto awọn de ibiti Alli duro si, nṣe ni mọto akero na ya kuro loju ọna ni ojiji ti o si lọ ba nibiti o duro si, ti o si gbe ṣabu.

Lojukanna ni gbogbo awọn ero inu mọto na ba sarẹ sọkalẹ lati ṣe itọju ọkunrin na ti o npoka iku ninu agbara ejẹ ati ẹmu, ṣugbọn ko pẹ pupọ lẹhi na ti ọkunrinna fi ku bamubamu.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn enia na ba sare gbe oku ọkunrin na lọ si Ile iwosan Lakuleku fun ayewo awọn Dokita.

Irohin awọn Ọlọpa fi ye wa pe, nwọn ti mu Dẹrẹba mọto na lati wadi awọn ọrọ kan lẹnu rẹ. Bi nwọn ba ti pari rẹ si, ẹ o ma a gbọ o.

# OBINRIN KAN PE ỌKỌ RẸ NI 'OKOBO'

AKURẸ:— Lẹnulọlọyi ni awọn Ọlọpa mu Ọdaran kan, Utoroh Emesinsi, ẹni Ọdun marundinladọta to o nṣẹṣẹ agbẹ wa si Ile ẹjọ ganran fun ẹsun apania.

Alaye ti awọn Ọlọpa ti o ba Ọdaran na ṣẹjọ ṣe niwaju adajọ ni wipe Ọdaran na mu iyawo rẹ, Iyaafin Obemu Emesinsi, ẹni Ọgbọn Ọdun lọ si oko wọn ti o wa ni Okitipupa ni Ọgbọnjọ Oṣu kẹfa Ọdun ti o kọja yi, o si lu Obinrin na pa bamubamu.

Irohin awọn Ọlọpa fi ye wa pe ẹjọ Apania ni nwọn ti mba Ọdaran na ro tẹlẹ ri. Ṣugbọn nwọn yi ẹjọ na si ẹjọ ijanba iku ojiji.

Ninu ẹjọ ti Ọdaran na ro niwaju adajọ lati fi gba ara rẹ kalẹ, o si alaye pe, edeaiyede kan ni o ṣẹlẹ ninu ile ti awọn ngbe, nibiti awọn si ti nsọ Ọrọ na ti gbogbo awọn aladugbo parajọ le awọn lori ni iyawo on ba mbu on ni awọn eebu ara.

Ọdaran na ni gbogbo eebu ti o ba on ti awọn enia ti o duro ti awọn mbẹ on pe ki on ni suru ko dun on.

Ṣugbọn nigbati awọn enia ri wipe on ko da a lohun ki eebu na o le ba dun, ni o ba pe on ni "Okobo".

Ọdaran na ni nigbati on gbọ bayi, ori on papo, ṣugbọn on mu suuru fun un de ibiti ọmọkunrin le mu suuru de.

Nigbati oju rẹ si wa lẹ ni on ba mu lọ si oko, on si fihan pe, on to ṣe dun on, ki iṣe pe on fẹ lu pa ni, eṣu lo lọwọ si ọran na ti o fi la iku lọ.

Nigbati Adajọ Ile-ẹjọ ganran na gbọ ọrọ yi, ni o ba ṣe idajọ pe, ki Ọdaran na lọ fi ẹwọn ọdun mẹwa jura.

# 'Adajọ Ṣe Aṣiṣe Ninu Idajọ Rẹ'

LATI OJU EWE KINI

na, ki o to san owo fun ni yio si ti gba iwe na lati fi pamọ.

Gbogbo Ile ẹjọ lo dakẹ si mikunlẹ nigbati Ọgbẹni Ayọọla sọ fun Ile ẹjọ pe Ọrẹdẹhin ko san Owo kankan fun Sumbọ Jibowu, ẹniti o ti ku ninu awọn Olujẹjọ na.

Oniwe Irohin wa Ejongboro ti o wa ninu Ile ẹjọ na ni on ri iya arugbo kan ti nfi aṣọ nu oju rẹ nigbati Omi Oju mbo loju iya na Ṣugbọn ko le sun ẹkun na jade nitori ninu kotu lo wa.

Ọgbẹni Ayọọla wa pari Ọrọ rẹ pe, Ọgbẹni Ọrẹdẹhin ko mọ on ti awọn enia ti o san owo fun fẹ fi owo ṣe, bẹni ko si ba wọn ṣe ipade ti nwọn ṣe ni oṣu kejila Ọdun 1961.

OYEṢILE

Lẹhinleyi ni Ọgbẹni Ayọọla pari ẹjọ enia keji ti o si bọsi ori enikẹta eyi ni Ọgbẹni Oyesile, ẹniti nwọn sọ pe awọn Ọlọpa ri nkan ija Ogun ninu ile rẹ ni Mushin.

Ọgbẹni Ayọọla ṣe alaye pe, Ọgbẹni Oyeṣile ko ba wọn lọ ipade ti nwọn sọ pe nwọn ṣe ni Ikẹnnẹ nibiti nwọn ni nwọn ti pin awọn nkan ija ogun.

Bi o ti nṣọ Ọrọ yi lọwọ ni Ọlọla adajọ Mbanefo bere pe, "Nje Oyeṣile wa nibẹ nigbati awọn Ọlọpa fi nwa awon nkan ija Ogun jade ni ẹhinkule rẹ ?" Ọgbẹni Ayọọla sọ pe, "gẹgẹbi ẹjọ ti nwọn ro, o wa nibẹ nigbana".

O wa pe akiyesi wọn si oju ewe kẹsan iwe idajọ (page 9) pe, awọn Ọlọpa sọ pe nigbati nwọn ko awọn nkan ija ogun na sinu agba gorodomu nla kan tan, nwọn de pa, nwọn gbẹlẹ nwọn si ri gorodomu na mọlẹ, nwon rẹ ogan gan ibẹ ni simẹnti ni ẹhinkunle.

Ọgbẹni Ayọọla wa ṣe alaye pe, Ọgbẹni Oyeṣile ko mọ awọn nkan ti nwọn npe ni nkan ogun, nitoripe ko mọ iwe nigbati nwọn si pe ni maṣinni, o ro pe maṣinni iranṣọ ni.

Gbogbo kotu lo bu si ẹrin nigbati adajọ ni ki nwọn lọ gbe maṣinni na wa ti Adedipe si fun Ọgbẹni Ayọọla ni ibọn pokiti kan.

Bi Ayọọla ti nyẹ ibọn na wo ti adajọ bere pe, "Maṣinni ni nwọn npe eyi" Bi Ayọọla ti fẹ dahun ibere na ti o si kọ oju ibọn si adajọ Agba, ni Ọlọla Adetokunbọ sọ pe, „Jọwọ ma kọju rẹ sọdọ mi o" Gbogbo Ile ẹjọ lo rẹrin, nwọn si gbe ibọn na pada si inu apoti.



Ọgbẹni J. S. Ọlawọyin

Ayọọla sọ wipe Henry Oleari ko sọ ninu ẹri ti o wa jẹ ninu ile ẹjọ pe Ọgbẹni Oyesile wa ninu awọn ti nwọn pin nkan ija ogun fun.

Lehin ni ọlọla Adajọ Brett wa bere pe, "Ṣe ọgbẹni Oyesile wa nibiti nwọn ti pin iṣẹ fun wọn?" Ọgbẹni Ayọọla sọ pe, ko si Oyeṣile ninu ipade na.

Ọgbẹni Durand simi ni ana o ti pari ọrọ rẹ ninu ile ẹjọ na ni jẹta, ṣugbọn ki o to pari ẹjọ rẹ, Ọgbẹni Durand ṣe alaye pe Dokita Maja ti nko awọn nkan ija ogun rẹ kakiri ki o to lọ ba Oloye Awolọwọ nile rẹ ni Ikoyi.

Durand ṣe alaye pe Oloye Awolọwọ ko si nile rẹ Ikẹnnẹ, nigbati awọn Ọlọpa lọ si ile rẹ, o si rọruh fun awọn ọta Awolọwọ lati lọ ko awọn ohun ọṣẹ na sinu ile rẹ nigbati nwọn mọ pe ko si Oloye na nile, ki nwọn lọ sọ fun awọn Ọlọpa ki nwọn si tun wa jẹri ninu ile ẹjọ.

Eyi ni pe nwọn le pe ole wa ja ki nwọn o si tun pe oloko wa ṣẹ oko" nitori ibuṣọ merindinlogọta ni Oloye Awolọwọ ki nwọn to ri nkan ogun ninu ile rẹ.

Ọgbẹni Ayọọla yio tun ma a ba ọrọ rẹ lọ ninu ile ẹjọ na ni owurọ yi.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga 17/464